# ÀGBÉYẸ̀WÒ ÌṢÀMÚLÒ EWÉ ÀTI EGBÒ ÌBÍLẸ̀ GẸ́GẸ́ BÍ Ọ̀NÀ ÀBÁYỌ SÍ ÌPÈNÍJÀ ÀÌLERA LÁTI ỌWỌ́

**ADÉKỌ̀YÀ, E. ỌLANIKẸ**

Adekoya.nike72@gmail.com **08038272565**

**Department of Nigerian Languages,**

**College of Languages and Communication Arts Education.**

**Lagos State University of Education, Oto/Ijanikin Lagos with Campus at Epe.**

**DOI:** https://doi.org/10.5281/zenodo.8324887

**Àṣamọ̀**

Ètò ìlera jẹ́ kòséémànì fún gbogbo ẹ̀dá ènìyàn, èyí kò sì yọ ẹ̀yà Yorùbá sílẹ̀ rárá. Ipò tí ètò ìlera wà fún gbogbo ènìyàn láti bi ọdún púpọ̀ sẹ́yìn láì sí ọ̀nà àbáyọ kan gbòógì láti ọ̀dọ̀ ìjọba fihàn pé ètò ìlera tolórí-tẹlẹ́mù ti mẹ́hẹ. Èyí ló gún olùwádìí ní kẹ́ṣẹ́ àgbéyẹ̀wò ọ̀nà àbáyọ tí àwọn ènìyàn ń lò láti wá ojútùú sí àwọn ìpèníjà àìlera tó ń ba ẹ̀dá fínra. Àfojúsùn iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí àwọn ènìyàn ń gbà láti wá ojútùú sí àwọn ìpèníjà àìlera wọ̀nyí. Ọ̀nà ìwádìí iṣẹ́ yìí jẹ mọ́ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò, àgbéyẹ̀wò àsọdàsílẹ̀ àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n bíi Orímóògùnjẹ́ (2015), Agbájé ninu Ilesanmi (1989) àti àwọn mìíràn tó ti ṣiṣẹ́ lórí iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ àti ìlera, pẹ̀lú wíwo àwọn ohun tó lè jẹ́ ojútùú àrọ́wọ́tó sí ìpèníjà àìlera fún mùtúmùwà. Tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ti Abímbọ́lá (1982) ni a ó fi ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí nítorí pé àfojúsùn iṣẹ́ yìí dúró lórí àfihàn oríṣìíríṣìí ìtagbọ́n-inú tí àwọn ẹ̀dá ń ṣe àmúlò láti wá ojútùú sí ìṣòrokíṣòro tó bá dé bá wọn pàápàá jùlọ èyí tó bá la ìlera lọ. Àbájáde iṣẹ́ yìí fi hàn pé látàrí àìní àti àìtó, àwọn ènìyàn ń tiraka ní ìlànà ìbílẹ̀ láti wá ọ̀nà àbáyọ àti ojútùú sí gbogbo ìpèníjà àìlera tó ń bá wọn fínra wọ̀nyí. Ó sì pọn dandan kí ìgbésẹ̀ tí ó tọ̀nà jẹ́ atọ́kùn sí ìlànà wọ̀nyí.

**Kókó ọ̀rọ̀:** Àìlera, ewé àti egbò ìbílẹ̀, ìpèníjà, ìṣàmúlò, ọ̀nà àbáyọ

## Ìfáárà

Àwọn àgbà káàkiri àgbáyé gbà pé iṣẹ́ ìjínjí, iṣẹ́ ààrọ̀-ọjọ́ niṣẹ́ ìṣègùn, pàápàá ìṣègùn ìbílẹ̀. Iṣẹ́ Elédùà ni pẹ̀lú."Àtẹ́wọ́ la bálà, a ò mọ ẹni tó kọ ọ́" ni ọ̀rọ̀ oògùn ìbílẹ̀ ní àwùjọYorùbá. Orímóògùnjẹ

(2015) ṣàlàyé pé láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni a ti ń já ewé tí a sì ń wa egbò fún ìdáàbòbò àti ìwòsàn ènìyàn láwùjọ wa. Olómù (2019) náà ṣàlàyé pé ọ̀sányìn ni Yorùbá gbà pé ó kọ́kọ́ ṣe ìwádìí àti àwárí ewé àti egbò gẹ́gẹ́ bí ohun tí a lè fi ṣe ìwòsàn oríṣìíríṣìí àrùn tó ń bá ẹ̀dá fínra, èyí tó padà wá sọ ọ̀sányìn dí òrìṣà ewé àti egbò ní ilẹ̀ Yorùbá. Kò síbìkan lórígun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ìṣálayé ti oògùn ìbílẹ̀ ò ti wúlò, bẹ́ẹ̀ ni kìí ṣe àìsàn tàbí àmódì nìkan leèyàn máa ń lo oògùn ìbílẹ̀ sí;ìwúlò rẹ̀ pọ̀ jọjọ jù bẹ́ẹ̀. Ohun ìwúrí ló jẹ́ láti ri pé oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá kò di ohun ìgbàgbé títí di àkókò yìí bí o tilẹ̀ jẹ́ pé èdè, ẹ̀sìn, ọ̀làjú àti àṣà ilẹ̀ òkèèrè ti sodo sí àwùjọ wa. Àwọn àgbà gbà pé bí àrùn tàbí àmódi kan bá ń ṣe wọn níbi kan, ewé àti egbò-igi tàbí èpo-igi yóò ti wà lágbègbè náà tí wọn ò lè máa fi wo irúfẹ́ àrùn tàbí àmódi náà sàn. Èdùmàrè dá ewé àti egbò fún ìlò ènìyàn àti ẹranko pẹ̀lú àwọn nǹkan abẹ̀mí gbogbo tí a lè rí àti àwọn tí a kò leè rí. O fi tewé tegbò ta tènìyàn tẹranko lọ́rẹ ni.

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní “ara líle ni oògùn ọrọ̀”. Èyí jásí pé Yorùbá ni ìgbàgbọ́ púpọ̀ nínú ìtọ́jú ara wọn. Ìtọ́jú ara nípa iṣẹ́ ìṣègùn ni ìlànà abínibí ti wà láwùjọYorùbá láti ìgbà tí ojú ṣì wà ní orúnkún, kí ìmọ̀ ìtọ́jú ara ní ìlànà tí olóyìnbó tó dé. Oríṣirísi ọ̀nà ni ìran Yorùbá ń gbà lo oògùn, wọ́n máa ń lò ó gẹ́gẹ́ bí àjẹsára, ààbò kúrò lọ́wọ́ ọ̀tá àti ìwòsàn fún oríṣirísi àìsàn ara bí i ibà, jẹ̀díjẹ̀dí, ìgbẹ́-ọ̀rìn, ikọ́-fée àti àtọ̀sí. Oògùn mìíràn wà tí ó jẹ́ pé wọn nílò ohùn-ẹnu (apè bíi ọfọ̀, ògèdè, àyájọ́, àásán abbl) kí ó tó lè ṣiṣẹ́ tí ó yẹ kí ó ṣe, bẹ́ẹ̀ àwọn mìíràn kò nílò ohùn-ẹnu rárá kí wọ́n to ṣiṣẹ́. Kí àwọn aláwọ̀ funfun tó gòkè odò wá ni ìlànà ìṣègùn ìbílẹ̀ ti gbilẹ̀ bí ọ̀wàrà òjò láwùjọYorùbá tí a sì máa ń lo oríṣìíríṣìí ọ̀nà láti wà ní àlàáfíà àti ara pípé. Ipò ìṣègùn ìbílẹ̀ láwùjọYorùbá kò ṣe e ́fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá yálà gẹ́gẹ́ bí àjogúnbá ni tàbí kíkọ́ lọ́dọ̀ oníṣègùn.

Yorùbá gbàgbọ́ pé àìsàn ti apá ìṣègùn òyìnbó kò bá ká, ẹsẹ̀ ọmọ ilé ló yẹ kí á fi tọ̀ ọ́. Ìyẹn ni pé ki a lọ fún ìwòsàn ni ìlànà ìbílẹ̀. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni irú àìsàn bẹ́ẹ̀ sì máa ń gbọ́ ìtọ́jú. Àwọn ènìyàn tilẹ̀ gbàgbọ́ péÁfíríkà ni olú ìbílẹ̀ egbòogi bí Abdulbaqi (2002) ti sọ. Ó jẹ́ kí ó yé wa pé ìmọ̀ yìí jinlẹ̀ ni orílẹ̀-èdè Áfíríkà tí ó fi jẹ́ pé ẹbí kọ̀ọ̀kan ló ni ìwé àkọ́ọ̀lẹ̀, ìyẹn àmọ̀sórí tó wọ́pọ̀ láwùjọ àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀, tí wọ́n fi ń mọ bí a ti ń tọ́jú onírúurú àìsàn. Òdú ni ìmọ̀ ìṣègùn ìbílẹ̀, kì í ṣe àìmọ̀ fún olóko, ó sì tún làmìlaaka káàkiri àgbáńlá ayé. Èyi lofà á ti iṣẹ́ yìí fi fẹ́ pe àkíyèsí gbogbo ọmọ Oòduà sí ìmọ̀ àtàtà yìí, pé o yẹ kí olúkúlùkù wa lè ní ìmọ̀ iṣẹ́ ìṣègùn ìbílẹ̀ yìí fún ìwúlò ìtọ́jú ara àti ẹbi wa, èyí tí a ó sì lè ṣe ní abẹ́lé wa láì ké gbàjarè sí ẹlòmíràn kí a tó lè ṣe èyí.

## Ọ̀nà Ìṣèwádìí

Ọ̀nà tí à gbá ṣe iṣẹ́ ìwádìí yìí jẹ mọ́ ìfọ̀rọ̀wánilẹwò. A ṣe èyí láti wádìí òkodoro ọ̀rọ̀ lẹ́nu àwọn abẹ́nà-ìmọ̀, wà lórí èrọ wọn nípa ìṣàmúlò ewé àti egbò ìbílẹ̀ fún ìwòsàn onírúurú àìsàn tó ń bá ẹ̀dá fínra láwùjọ. Bákan náà, a tún ṣe àyẹ̀wò sí iṣẹ́, àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan lórí kókó ọ̀rọ̀ ìwádìí fún iṣẹ́ ìwádìí tó kúnjú òṣùwọ̀n.

## Tíọ́rì Àmúlò

Ìlò ewé àti egbò jẹ mọ́ àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí a tí ṣe é ní àlàyé síwájú. Ìdí nìyí tí a fi yan tíọ̀rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò láàyò fún iṣẹ́ yìí. Ohun tí àwọn agbátẹ̀rù tíọ̀rì yìí ń fúnka mọ́ náà ni ọ̀nà láti dáàbò bo àṣà àti ìṣe àwùjọ kan. Nítorí ńàa, ohun tó gbọ́dọ̀ jẹ́ lámèyítọ́ lógún ni ṣíṣe àfihàn irú àwọn àṣà tó súyọ nínú iṣẹ́ ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀. Abímbọ́lá (1982:78) fìdí èyí múlẹ̀ nínú àlàyé rẹ̀ pé:

> Kí a tó lè rí ìlànà lámèyítọ́ lítíréṣọ̀ tí yóò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà, a ní láti jẹ́ kí irú ìlànà bẹ́ẹ̀, bí ó tí wù kó jẹ́ ti òde òní tó, ni ọwọ́ àṣà Yorùbá nínú, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, òfegè lásán ni iṣẹ́ lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ yóò jẹ́.

Adéyẹmí (2006:25) fìdí ọ̀rọ̀ Abímbọlá yìí múlẹ̀, Ó là á hàn wá pé kò sí bí a ṣe lè yọ ọwọ́ kílàǹkó àṣà kúrò nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ó gbà pé ojúṣe ònkọ̀wé ni láti ṣe àwárí àwọn àṣà ìbílẹ̀ tó ti forí mù kí wọ́n sì ṣe àfihàn wọn lọ́nà tí yóò fi gbé àṣà adúláwọ̀ láruge. Abala méjì ni àwọn agbátẹ̀rù tíọ̀rì yìí pín sí; àkókò ní àwọn tó rí àṣà gẹ́gẹ́ bí ohun tí kò gbọdọ̀ yípadà bíná ń jó, bójò ń rọ̀. Ká fọwọ́ lẹ́rán, ká máa wòye ni ọ̀rọ̀ àṣà jẹ́ lójú àwọn ọwọ́ yìí. Àwọn ọwọ́ kejì ló gba àṣà gẹ́gẹ́ bí atáyẹ́ṣe. Ohun tí wọ́n gùnlé ni àkójọpọ̀ àwọn àṣà tó lè ṣe àwùjọ ní àǹfàání tó sì le mú-un tẹ̀síwájú. Irúfẹ́ àṣà yìí wúlò fún ìtanijí àwùjọ. Tí a bá wo àwùjọ wa, oríṣìíríṣìí àṣà ló wà, èyí tí ìṣègùn ìbílẹ̀ jẹ́ ọ̀kan, nínù èyí tí a ti ń ṣe àmúlò ewé àti egbò fún ìwòsàn onírúurú ìpèníjà àìlera. Bí àwọn agbátẹ̀rù tíọ̀rì yìí ṣe pín sí ọwọ́ méjì, náà ni ìṣàmúlò ewé àti egbò ìbílẹ̀ ṣe é mú lò fún iṣẹ́ rere ni èyí tó lè mú ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè bá àwùjọ àti àwọn ènìyàn inú rẹ̀. Lọ́nà kejì ẹ̀wẹ̀, ewé àti egbò ṣe é múlò fún iṣẹ́ ibi, èyí tó lè mú ìfàsẹ́yìn bá àwùjọ tàbí àwọn ènìyàn tí a bá lò ó fún. Tí a bá fi ojú-inú wo àwùjọ wa, a ó ri pé méjèèjì ló pésẹ̀ síbẹ̀. Ìyẹn ni pé bí àwọn ènìyàn ṣe ń lo ewé àti egbò ìbílẹ̀ láti fi ṣe àwọn ènìyàn àwùjọ ni àǹfàání, náà ni àwọn mìíràn ń lò ó láti fi ṣe ènìyàn ní ìjàǹbá tàbí aburú ni èyí tó lè la ẹ̀mí lọ. Èrò àwọn agbátẹ̀rù ọwọ́ kejì yìí ni ó bá wá lára mu tí a sì faramọ́. Nítorí náà, ẹ̀yìn wọn ni a ó pọ̀n sí láti túṣu délẹ̀ ìkòkò ohun tó mumú láyà wa nínú iṣẹ́ yìí.

## Èrò Àwọn Onímọ̀ lórí Oògùn Ìbílẹ̀

Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ni wọn ti ṣíṣẹ́ lórí oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá. Lára wọn ni Fáṣehùn àti Adébóyè (2019), Àránsí (2017), Rájí (2014), Òjó (2009), Oyèlákin (2019), Rájí (1991), Agbájé nínú Ilésanmí (1989), àti àwọn mìíràn. Fáṣehùn àti Adébóyè (2019) jẹ́ kí ó yé wa pé láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni bí a tí ń ja ewé,wa egbò fún ààbò tàbí ìwòsàn ti wà láàárín àwùjọ wa.Ohun tí a fi ń yé wa ni pé lílo ewé àti egbò fún ìwòsàn ní ìlànà ti abínibí ti wà láti ìgbà ti ojú ṣì wà ní orúkún. Àránsí (2017) náà kò ṣài ṣe é ní àlàyé pé:

> Ó dájú pé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀ ni ìmọ̀ nípa oògùn ti wà. Ìlànà ìṣègùn jẹ́ àtọwọ́dọ́wọ́ nínú èyí ti àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ń ṣe àmúlò ewé àti egbò-igi fún ìdènà àìsàn àti ìwòsàn ara.
>
> Àlàyé Àránsí nípa oògùn ìbílẹ̀ ni pé láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni ó ti wà ní àwùjọ wa. Àwọn ènìyàn àwùjọ sì máa ń ṣe àmúlò ewé àti egbò-igi wọ̀nyí fún ìdáàbòbò àti ìwòsàn kúrò lọ́wọ́ onírúurú àìsàn àgọ́ ara. Rájí (2014) náà kò gbẹ́yìn. Àlàyé ti òun ṣe nípa oògùn ìbílẹ̀ ni pé: Oògùn ṣíṣe jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn Yorùbá fi ń dáàbò bo

> ara wọn.Oríṣìíríṣìí oògùn ló wà… a lè lo oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá fún ààbò àti iṣọ́ra-ẹni, ìlú tàbí orílẹ̀-èdè ẹni.

Àyọlò òkè yìí ń fi yé wa pé yàtọ̀ sí pé à ń fi oògùn ìbílẹ̀ ṣiṣẹ́ ìwòsàn, a tún lè lò ó fún ìdáàbòbò tàbí ìgbara-ẹni-kalẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ẹ̀mí àìrí tàbí ọ̀tákọ̀tàá tó bá ń yọ ayé wa lẹ́nu. Fáṣehùn àti Adébóyè (2019) sọ nípa èrò Ọmọ́wùmí (2012) nípa oògùn ìbílẹ̀ ni pé;

> Yorùbá tún gbàgbọ́ pé ìjàm̀bá, ìpalára àti iwọ jíjẹ á máa rán ènìyàn ni ọ̀run ọ̀sán gangan ìdí nìyí tí wọ́n fi gbà pé ènìyàn lè ṣe oògùn nítorí iwọ jíjẹ àti ìjàm̀bá òjijì.

Ọ̀rọ̀ Ọmọ́wùmí yìí fihàn pé Yorùbá nífẹ̀ẹ́ oògùn ṣíṣe nítorí àti bọ́ lọ́wọ́ ewu àti àwọn ìdojúkọ mìíràn nínú ìgbòkègbodò wọn nílé ayé. Ajíkòbi (1999) náà fìdi rẹ̀ múlẹ̀ pé:

> Nǹkan kan tó dájú tó ọṣẹ ni pé kò sí ibìkan lórígun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ìṣálayé tóògùn ìbílẹ̀ ò ti wúlò, … kìí ṣe àìsàn tàbí àmódi nìkan lèèyàn máa ń lo oògùn ìbílẹ̀ sí, ìwúlò rẹ̀ pọ̀jọjọ jù bẹ́ẹ̀.

Àlàyé Ajíkòbi ni pé káàkiri orígun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin àgbáńlá-ayé ni wọ́n ti ń ṣe àmúlò oògùn ìbílẹ̀, ibi gbogbo ṣá à ni Yorùbá ti sọ pé a ti ń dáná alẹ́. Ó jẹ́ kí ó yé wa pé kìí ṣe àìsàn nìkan ni a ń fi oògùn ìbílẹ̀ wò, a tún máa ń lò wọ́n fún àwọn ohun mìíràn. Ọsọbà àti Ọ̀ṣọ́ (2016) jẹ́ kí ó yé wa pé lára àṣà Yorùbá ni oògùn ìbílẹ̀ wà, àti pé Yorùbá kò kóyán àṣà wọn kéré rárá. Wọ́n ṣàlàyé pé nínú àṣà Yorùbá ni ìlò oògùn wà, ati pe hun tí ó gùn ti ko lopin ni à ń pè ní oògùn. Àlàyé wọn yìí fi yé wa pé ìran tó káràmásìkí àṣà ni ìran Yorùbá jẹ́, wọn kò sì fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú-un rárá. Lára àwọn àṣà wọ̀nyí si ni oògùn ìbílẹ̀ wà.

Ìwòye Adéloyè (2015) ni pé wíwo àrùn sàn ni ìlànà ìbílẹ̀ Yorùbá lè jẹ mọ́ oògùn lílò (charm), ọfọ̀ pípè (incantation), àdúrà gbígbà àti àwọn ọ̀nà mìíràn. Ó ṣàlàyé pé bí àrùn ọpọlọ bá ṣẹlẹ̀, ọgbọ́n-ìdá oògùn ajẹmọ́pọlọ (psychotherapy) ni Yorùbá máa ń lò, wọn á sì lo ewé àti egbò-igi fún àwọn àìsàn tó bá hànde.

Nígbà tí Oyèbámijí (2016) yi ri iṣẹ́ Fádípẹ̀ (1970) wò nípa oògùn ìbílẹ̀, ó yanana rẹ̀ pé Fádípẹ̀ pín oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá sí ọ̀nà méje: (1) Awàrùnsàn (curative), (2) mọ́jẹ̀lé (poison), (3) Àpèta/Àfikàn (charm/hamlets), (4) Ajẹméèwọ̀ (Taboo), (5) Èpè (curse), (6) Oṣó àti Àjẹ́ (witchcraft and sorcery), (7) oògùn Ajẹmẹ́sìn (Religious Medicine). Fádípẹ̀ wá ṣàlàyé pé bí oògùn ṣe lè jẹ mọ́ agbára ẹ̀mí àìrí tàbí ohun ìkọ̀kọ̀, bẹ́ẹ̀ ni a rí oògùn tó jẹ mọ́ àkójọpọ̀ egbòogi tó lọ ni ìlànà ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì. Èyí ni ìlànà oògùn tó jẹ mọ́ tewétegbò tí a lè fojú rí tàbí fi ọwọ́ kàn, kí á sì ṣe àkíyèsí ọ̀nà tó ń gbà ṣiṣẹ́. Ẹ gbọ́ ohun tí Fádípẹ̀ sọ:

> Bí a kò tilẹ̀ fi gbogbo ẹnu sọ pé àwọn Yorùbá ni oògùn tó faramọ́ ìlànà ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì, a lè sọ pé wọ́n máa ń ṣe àkójọpọ̀ egbòogi tí àlàyé ọ̀nà tí wọ́n gbà kó o jọ àti ìlànà

iṣẹ́ rẹ̀ máa ń ṣe é ṣàlàyé. Lára àwọn irú àkójọpọ̀ oògùn báyìí ni oògùn awàrùnsàn (curative medicine) wà.

Èrò Fádípẹ̀ àti Adéloyè yìí fara pẹ́ra. Àwọn méjèèjì ni wọ́n gbà pé bí ìlò tewétegbò ṣe wà fún wíwo àrùn-sàn, bẹ́ẹ̀ náà ni Yorùbá máa ń lo ohùn-ẹnu (apè-ọfọ̀, àyájọ́, ògèdè, ààsàn) láti kápá àwọn àìsàn kan.

Oyèbámijí (2016) tún tẹ̀síwájú láti tọpinpin ohun ti Johnson (2009) ṣe ni àlàyé nípa oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ó ní àwọn ènìyàn kan wà tí a lè pè ní Dókítà gẹ́gẹ́ bí ìṣe wọn, pé àwọn wọ̀nyí ni àwọn ẹni àsárépè/àsárétọ̀ bí nǹkan kan tàbí àìsàn òjijì bá yọjú. Orúkọ wọn ni Adáhunṣe. Johnson fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí ilé ìwòsàn kan pàtó, síbẹ̀ àwọn Adáhunṣe wọ̀nyí ti ṣe àwárí àwọn tewétegbò kan ti wọn ń fi kojú/kápá àwọn àìsàn bíi ẹ̀tẹ́ (leprosy), àrùn ọpọlọ (insanity), ọgbẹ́-inú líle (chronicle ulcer) abbl.

Tí a bá wo gbogbo àlàyé tí a ti ń ṣe bọ̀ nípa ohun tí àwọn onímọ̀ ti sọ lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan nípa oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá, ohun tí a rí fàyọ níbẹ̀ ni pé ọ̀nà méjì pàtàkì ni a lè pín oògùn ìbílẹ̀ Yorùbá sí, àwọn ni: (1) oògùn ajẹmọ́ tewétegbò àti (2) oògùn tó ní í ṣe pẹ̀lú ìmísí Olódùmarè àti pípè tàbí lílo àwọn ẹ̀mí àìrí kan, tí a tún lè pè ní idán. Bí tewétegbo ṣe wà fún ire láti fi gba ènìyàn là, bẹ́ẹ̀ náà ni àwọn ènìyàn búburú tún lè lò ó lọ́nà tí kò dára. Bákan náà, wọ́n tún máa ń lo àwọn oògùn ajẹmọ́dán àti ẹ̀mí àìrí lọ́nà ire àti ibi pẹ̀lú. Oògùn tó jẹ mọ́ tewétegbò ni a fẹ́ ṣe àfihàn rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí àti bí wọn ṣe ń lò ó fún ìdáàbòbò àti ìwòsàn onírúurú àìsàn.

### Ìpínsísọ̀rí Oògùn Ìbílẹ̀

Nígbà tí Fáṣehùn àti Adébóyè (2019) ń ṣàlàyé nípa ohun tí Agbájé (1989) sọ nípa ìpínsísọ̀rí oògùn ìbílẹ̀, wọ́n ní láti ìgbà láéláé ni oògùn ìbílẹ̀ ti wà gẹ́gẹ́ bí a ti fìdí rẹ̀ múlẹ̀. Ní àwùjọ Yorùbá, àwọn oníṣègùn a máa wà níbẹ̀ láti máa jáwéjágbò fún ìwòsàn yòówù ní àwùjọ náà. Ìgbàgbọ́ àwọn wọ̀nyí rọ̀ mọ́ agbára tó sodo sínú ewé, egbò àti oríṣìíríṣìí àgbò tí wọ́n ń ṣe àmúlò rẹ̀, èyí sì máa ń jẹ fún àìsàn yòówù tí wọ́n bá lòó fún. Ìlò ewé àti egbò náà ni a tún mọ̀ sí egbògi tàbí àgbo ìbílẹ̀, lílò rẹ̀ sì wọ́pọ̀ láàárín Ẹ̀gbá, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀ṣà, Ọ̀yọ́, Èkìtì, Oǹdó àti àwọn agbègbè Yorùbá yòókù. Ìpèsè àti àmúlò wọn kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ síra, àmọ́, ohun tí ó lè fa ìyàtọ̀ ní èdè àti àṣà ìlú tàbí agbègbè kọ̀ọ̀kan.Wọ́n jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé àwọn ewé àti egbò kan wà tí wọn nílò ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ kí wọn tó lè ṣiṣẹ́ tí wọn fẹ́ lò wọ́n fún, bẹ́ẹ̀ ni àwọn mìírán sì nílò ètùtù kan tàbí òmíràn pẹ̀lú.

Onírúurú àwọn onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí ìpínsísọ̀rí oògùn ìbílẹ̀ ní ìbámu pẹ̀lú èròjà àti iṣẹ́ ti wọn ń ṣe. Adéoyè (2005) pín oògùn ìbílẹ̀ sí oògùn awàrùnsàn àti oògùn ìkà. Ọmọ́wùmí (2012) ní tirẹ̀ pín-in sí oògùn ìtọ́jú alátọ̀sí, oògùn ìtọ́jú àìsàn èèdì, ìfètò-sọ́mọ-bíbí, oògùn mágùn, tẹ̀ṣọ̀ọ́, oyún títọ́jú, ìgbẹ̀bí aláboyún, ààbò àti ìtọ́jú ìyá ìkókó. Rájí (2014) náà pín oògùn ìbílẹ̀ sí àwọn ìsọ̀rí bíi oògùn agbára fún ààbò ara, oògùn ogun, Àjáǹgbà oògùn, oògùn tí a fi ń tẹ́ ènìyàn, ìdán-àn-gùn, oògùn àṣẹ, oògùn fún ìtọ́jú àti ààbò ara, oògùn ìwòsàn, oògùn ìwúre, oògùn ẹ̀rọ̀, oògùn ẹbọ, Ebu ifá, oògùn ìfẹ́ràn àti oògùn àṣẹ. Oyèbámijí (2016) tọ́ka sí ìpínsísọ̀rí Fádípẹ̀ (1970) nípa oògùn ìbílẹ̀

Yorùbá, èyí ni ó pín sí oògùn awàrùnsàn, mọ́jèlé, àpèta/àfikàn, ajẹméèwọ̀, èpè, ọṣó àti àjẹ́ pẹ̀lú oògùn ajẹmẹ́sìn.

Tí a bá wo àwọn ìpínsísọ̀rí oògùn ìbílẹ̀ tí àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n ti ṣe yìí, a ó ri pé onírúurú bi aṣọ alágẹmọ ni ọ̀rọ̀ oògùn ìbílẹ̀ jẹ́. Oríṣìíríṣìí ọ̀ṣùwọ̀n ni a lè lò láti pín oògùn ìbílẹ̀ tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí yálà nípa orírun, èròjà àti ohun tí ó wúlò fún. Tí a bá gùnlé èyí, yóò jẹ́ kí a lè pín-in sí ọ̀nà méjì gbòógì tí í ṣe oògùn fún ìwòsàn àti oògùn fún ààbò.

**Oògùn Ìwòsàn**

Orísìírísìí ni irúfẹ̀ oògùn yìí lè jẹ́ bíi àgbo, àgúnmu tàbí èjó-oògùn. Àpẹẹrẹ oògùn àfọwọ́fà bíi àrùn onígbáméjì, ìgbẹ́-gbuuru, ìgbẹ́-ọ̀rìn, ikọ́-ife, oògùn akokoro yọ̀rọ̀. Oògùn àfarafà bíi oògùn ẹ̀rọ̀ mágùn àti ti àtọ̀sí. Oògùn àrùn ọkàn bíi ẹ̀jẹ̀-rírú àti oògùn àrùn ọpọlọ bíi ìdàrú-èdè náà wà lára oògùn ìwòsàn yìí.

**Àtúpalẹ̀ Détà àti Ìjóròrò àbọ̀ Ìwádìí**

Ìwádìí tí a ṣe fihàn pé ọ̀nà ìṣègùn ìbílẹ̀ nípa ìlò ewé àti egbò pín sí oríṣìíríṣìí ọ̀nà, lára wọn ni gbẹ́rẹ́ sínsín, alágùn-únmu, alásèjẹ, alágbomu, alábùwẹ̀, aláfipara àti ọfọ̀ (ohùn ẹnu).

**Ìwúlò ewé àti Egbò**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà ni ewé àti egbò gbà wúlò fún ẹ̀dá. Lára àwọn ọ̀nà náà ni pé:

- Ó wúlò fún ìwòsàn àti ìlera pípé
- Ó ń fún ẹ̀dá ni oúnjẹ
- Ó ń pèsè aṣọ nítorí òwú ni a fi ń ṣe aṣọ tí ẹ̀dá ń wọ̀.
- Ìmọ̀ ewé àti egbò ń fún èniyàn ni agbára yálà rere ni tàbí búburú.
- Ìmọ̀ rẹ̀ ń pèsè iṣẹ́ fún èniyàn
- Ìmọ̀ ewé àti egbò ń mówó wọlé fún èniyàn
- Ó wúlò fún ohun mímu ìgbafẹ́
- Ewé àti egbò ń so ìlú di olókìkí
- Ó ń mú ìdàgbàsókè ba ọrọ̀-ajéÌlú.
- Ewé àti egbò ń mú ìlú gbòòrò si. Bí àpẹẹrẹ ti ìlú kan bá mọ̀ pé oúnjẹ àti ohun èlò ìwòsàn wà ní ìlú mìíràn, wọn yóò bá irúfẹ́ ìlú bẹ́ẹ̀ dòwò pọ̀.

**Àléèbù Ewé àti Egbò**

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní "tibi tire la wáyé". Kò sí ohun tó dára tí kò ní ìdàkejì rẹ̀, ṣe "ọmọ kìí dára títí kò má kù síbìkan" ni Yorùbá wí. Bí ewé àti egbò ṣe dára tó náà ni ó tún burú jàì látàrí iṣẹ́ búburú tí àwọn ìkà èniyàn fi ń ṣe. Díẹ̀ lára àwọn àléèbù náà nì wọ̀nyí:

- Ó jẹ́ bí agbára burúkú fún àwọn ìkà èniyàn.
- Nígbà mìíràn, ìlò rẹ̀ kò ní òduwọ̀n.
- Díẹ̀ díẹ̀ ló máa ń ṣiṣẹ́, kò dàbí abẹ́rẹ́ òyìnbó.

- Ó lè tún mú àìsàn mìíràn jẹyọ lára ènìyàn
- Ó ń pa ènìyàn.
- Nígbà mìíràn, oògùn ìbílẹ̀ kan lè wo igba àrùn. A rí èyí lára oògùn òyìnbó náà tí ó ń wò ju ẹyọ àrùn kan lọ. Àwọn àgbà a máa sọ pé "ọ̀kánjúà oògùn ló ń jẹ́ gbogbonìṣe".
- Àìtẹ̀lé ìlànà tí a là kalẹ̀ fún ìlò egbòogi náà.
- Ìkùnà láti pe ohùn-ẹnu (apè: ọfọ̀, ògèdè, àyájọ́, ààsán) tó tọ́sínú egbòogi kí ó tó di lílò, tó bá jẹ́ èyí tó nílò apè nínú.

**Àìsàn Ibà Pọ́njú-Pọ́ntọ̀**

Irúfẹ́ àìsàn yìí jẹ́ ọ̀kan lára onírúurú àìsàn tó máa ń bá ẹ̀dá jà ní àgọ́-ara. Tí a bá wò ó, gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, pọ́njú-pọ́ntọ̀, ó jẹ́ àìsàn tó máa ń mu kí ọmọlójú ènìyàn méjèèjì rẹ̀ dòdò bí òdòdó. Bákan náà, ìtọ̀ ẹni ti àìsàn yìí bá wà ni àgọ́-ara rẹ̀ yóò pọ́n pẹ̀lú. Àìsàn yìí máa ń mú kí ó máa rẹ ènìyàn láti inú wa, o sì tún máa ń mú àìṣe-dédé bá àgọ́-ara ènìyàn. Nígbà míìràn ẹ̀wẹ̀, ó máa ń fa kí ènìyàn máa sùn lóòrèkóòrè.

**Àwọn àmi àìsàn ibà pọ́njú-pọ́ntọ̀.**

Oríṣìí ọ̀nà mẹ́ta ni a lè gbà dá ènìyàn tó ni ibà pọ́njú-pọ́ntọ̀ mọ̀. Àwọn ọ̀nà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà nì wọ̀nyí:

- Kí ẹyinjú ènìyàn pọ́n tàbí kí ó rẹ̀ dòdò.
- Kí ìtọ̀ ènìyàn pọ́n ràkọ̀ràkọ̀.
- Kí ènìyàn máa sùn nísẹ̀ẹ́ju-ìṣẹ́jú.

**Onírúurú egbòogi fún ìtọ́jú àìsàn ibà pọ́njú-pọ́ntọ̀**

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan egbòogi ló wà tí a lè fi kápá irúfẹ́ àìsàn yìí. Díẹ̀ nínú wọn nì wọ̀nyí:

- Ewé ejìnrìn, ẹmu ògùrọ̀, omi ọsàn
- Àwopa àti ẹmu tàbí ògùrọ̀
- Èpo máǹgòrò, ewé tìì, esùsú pupa, ọṣẹ pupa, pòròpóròọ̀ ọkàababà, kánún àti omiídùn.
- Egbò ẹ̀gbẹ̀sì, egbò ọsàn wẹ́wẹ́
- Ewé tàbí egbò òruwọ, egbò pérù, òrombó wẹ́wẹ́, omi ògì àti ẹ̀kọ yangan
- Èpo awùn, èpo máǹgòrò, èpo àrunjẹ àti ẹ̀mì ọ̀pẹ
- Ahọ́n erin, oyin àti omi ọsàn wẹ́wẹ́.

**Àlàyé nípa Ìlò àwọn egbòogi wọ̀nyí.**

- Ewé ejìnrìn yìí ni a ó fi omi ọsàn wẹ́wẹ́ tàbí ẹmu ògùrọ̀ kì ní àgbo, a ó fi sílẹ̀ fún bí ọjọ́ mẹ́ta láti tọró. Ní ọjọ́ kẹta, aláìsàn yóò máa mu gàásì kọ̀ọ̀kan ní àárọ̀ àti alẹ́. Èyí yóò mú kí ó máa tọ ibà náà jáde.
- Èpo àwọpa yìí ni a ó kì pẹ̀lú ọtí ìbílẹ̀ (ògògóró). A ó fi sílẹ̀ fún odindi ọjọ́ mẹ́ta láti jẹ́ kí ó tọró. Lẹ́yìn ọjọ́ kẹta, ó ti di mímu nìyẹn, gàásì kọ̀ọ̀kan ni àárọ̀ àti alẹ́.
- Èpo máǹgòrò, ewé tìì, esùsù pupa, ọṣẹ pupa, pòròpóròọ̀ ọkàababà àti kánún, a ó ṣan wọ́n, a o sì kó gbogbo rẹ̀ sínú orù tí ó mọ́, a ó bu omi sí i fún sísè lórí iná. Tí ó bá ti jiná, ó ti délè fún mímu nìyẹn. Kọ́ọ̀bù kékeré kan láàárọ̀ àti alẹ́.

- Egbò ọ̀gbẹ̀sì, egbò ọsàn wẹ́wẹ́, a ó fi omiídùn (omi-ògì) sè é fún mímu ni ààrọ̀ àti alẹ́. Kọ́ọ̀bù kékeré kan ti tó.
- Ewé tàbí egbò òruwọ, egbò fẹru àti òrombó wẹ́wẹ́, a ó ò gé òrombó wẹ́wẹ́ yìí sí ọ̀nà mẹ́waá, a ó fi omi-ògì sè é fún mímu lẹ́ẹ̀meta lójúmọ́.
- Èpo awùn, èpo máńgòrò àti èpo àrunjẹ (ni a ó ò fi tẹ́lẹ̀ ìkòkò àgbo náà) ni a ó sè papọ̀ pẹ̀lú ẹmu ọ̀pẹ̀ tàbí omiídùn. A ó máa mu kọ́ọ̀bù kékeré kọ̀ọ̀kan ni ààrọ̀, ọ̀sán àti alẹ́.
- A ó po omi-ahọ́n erin (Aloevera), omi ọsàn wẹ́wẹ́ àti oyin papọ̀ sínú kọ́ọ̀bù kékeré kan, a ó sì mu-un tán lẹ́ẹ̀kan náà. Yàtọ̀ sí èyí, a tún lè ṣe àmúlò èpo igi máńgòrò, ìrèké àti ọ̀pẹ̀yìnbó. A ó gé wọn sí wẹ́wẹ́ láti sè é lórí iná. Tí o bá ti jiná tán, aláìsàn yìí yóò fi aṣọ bora papọ̀ mọ́ àgbo náà títí yóò fi làágùn jáde, lẹ́yìn èyí yóò fi àgbo náà wẹ̀. Kọ́ọ̀bù kékeré kọ̀ọ̀kan fún mímu láàárọ̀ àti alẹ́.

**Dídènà Àìsàn Ibà Pọ́njú-pọ́ntọ̀**

Lára àwọn ọ̀nà tí ènìyàn lè gbà dènà àìsàn pọ́njú-pọ́ntọ̀ nì wọ̀nyí:

- Ìmọ́tótó nípa omi tí à ń mu ṣe pàtàkì. Ó gbọ́dọ̀ jẹ omi tó mọ́ tó sì dára fún mímu.
- Ìmọ́tótó àyíká náà ṣe pàtàkì, kí a máṣe dí ojú àgbàrá pẹ̀lú ìdọ̀tí.
- Àwọn ohun tí à ń jẹ sínú náà gbọ́dọ̀ jẹ èyí tó kógo ìdọ̀tí já.
- Kí a máa ṣe àmúlò àwọn egbòogi fún àìsàn yìí, ó kéré jù, oṣù mẹ́ta-mẹ́ta láti lè dènà àìsàn ibà pọ́njú-pọ́ntọ̀ yìí ni wiwọ inú àgọ́-ara wa.

**Àìsàn Awọ̀ Ara**

Ìwádìí ti a se fi yé wa pé oríṣìíríṣìí àìsàn àwọ̀-ara ló wà, lára wọn ni kúrúnà, ẹ̀tẹ̀, irorẹ́, ẹ̀yi abbl. Gbogbo ara ni irú àwọn àìsàn yìí ti lè mú ènìyàn (Ajélétí,2008).

**Àìsàn Ẹ̀yi**

Àìsàn ẹ̀yi jẹ́ àìsàn tí ó máa ń bá àwọ̀ ara ènìyàn jẹ́, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ènìyàn tí kò lè mú yálà ọmọdé ni tàbí àgbàlagbà. Àwọn onímọ̀ ìṣègùn òyìnbó náà fi yé wa pé kòkòrò àìfojúrí ló máa ń fa àwọn àìsàn yìí (Adétuyibi, 1980). Nígbà mìíràn, ẹ̀yi máa ń fa egbò kín-kìn-kín lára ọmọdé tí yóò sì máa sun omi jáde, àmọ́ tó bá jẹ́ ara àgbàlagbà ni, ń ṣe ni yóò máa gbẹ onítọ̀ún ni àwọ̀ ni.

**Bi a ṣe lè dá ẹ̀yi mọ̀**

**Ara híhún:** Eyi jẹ ẹ̀yà ìdámọ̀ àìsàn ẹ̀yí. Ẹni tí àìsàn yìí bá ń bá fínran yóò máa họ ibi tí àìsàn yìí wà ní àhọbó ni, ibẹ̀ yóò sì máa ta aláìsàn yìí lẹ́yìn híhọ.

**Irú Oúnjẹ Tí Aláìsàn yìí Gbọ́dọ̀ Jẹ:** Oríṣìíríṣìí àwọn oúnjẹ aṣaralóore, tí ó sì lè mú ara dán ni aláìsàn yìí gbọ́dọ̀ máa jẹ nígbà gbogbo. Àwọn oúnjẹ bíi ẹ̀wà, ẹyin, ẹran, ẹja abbl. Àwọn oúnjẹ

onítáàṣì bíi iṣu, àmàlà, iyán, ẹ̀bà, ẹ̀kọ, pẹ̀lú oúnjẹ ọlọ́ràá bíi òróró, ẹ̀pà, òróró ẹ̀gúsí, epo pupa kò gbọdọ̀ jẹ́ èèwọ̀ fún aláìsàn yìí. Yàtọ̀ sí èyí, ó tún gbọ́dọ̀ máa jẹ àwọn oriṣiíríṣìí èso àti ewébẹ̀ pẹ̀lú.

**Èròjà Iwòsàn Ẹ̀yi:** Lára àwọn ohun tí a lè fi kápá àìsàn ẹ̀yi ni ọṣẹ-dúdú, osùn, oyin gidi, aloféra àti dìtọ́ọ̀lù.

**Ìpèsè èròjà àìsàn Ẹ̀yi**

Osùn ìwọ̀n bí agolo tòmátò ìdaji kan, oyin agolo mílíìkì kan, oje funfun inú aloféra ìwọ̀n agolo mílíìkì kan pẹ̀lú dìtọ́ọ̀lù ẹ̀kún agolo tòmátò kékeré kan, a ó ò gún gbogbo rẹ̀ papọ̀ nínú odó kékeré kan. Lẹ́yìn èyí, a ó fi ọṣẹ dúdú tí ó lè gbé gbogbo wọn mì papọ̀ kó wọn nínú odó náà, a ó sì tọ́ju rẹ̀ sínú ike ọlọ́mọrí kan fún wíwẹ̀ lójoojúmọ́. Lẹ́yìn ìwẹ̀, a ó máa fi oje-inú aloféra tí a ti pò papọ̀ mọ́ gírísì para lójoojúmọ́ títí gbogbo kòkòrò yìí yóò fi fẹsẹ̀ fẹ́ẹ ni àgọ́-ara aláìsàn. Ó ṣe pàtàkì láti ṣàlàyé pé tí a kò bá tún fẹ́ gba irúfẹ́ àìsan yìí lálejò mọ́, ki a kúkú yan àpòpọ̀ ọṣẹ gígún yìí láàyò ní wíwẹ̀ nígba gbogbo.

**Àgbálọgbábọ̀**

Láì deena penu, ìran Yorùbá gbàgbọ́ pé ara kìí ṣe òkúta, ẹni tí ó wà lálàáfíà ni ó lè ṣayé. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ní ètò pàtàkì tí àwọn bàbá-ńlá wa ṣètò kalẹ̀ láti kojú gbogbo àrùn tàbí ìpèníjà àìlera tí ó bá fẹ́ kojú ẹ̀dá. Pépà yìí ṣe àfihàn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà ṣe ìṣègùn wọn, a sì túṣu dé ìsàlẹ̀ ikòkò àǹfààní ewé àti egbò gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àbáyọ sí àìlera ẹ̀dá pàápàá jùlọ ni àwùjọ tí ìṣègùn òyìnbó kò ṣe é kàn fún kò-là-kò-ṣagbe. Àwọn tí iṣẹ́ ìṣègùn wà ní ìkáwọ́ wọn a máa ki ara wọn láti fí pàtàkì ewé àti egbò hàn láwùjọ Yorùbá wí pé:

Ọmọ ajáwé diwé
Ọmọ ajáàgùn diìgùn
Ọmọ ewé méjì oògùn
Ọmọ a sọ̀kò sínú àdó
Ó ṣàkùrọ́ sójú ọ̀sanyìn
Ọmọ ewé gbogbo kìkì oògùn
Ọmọ lò ó lò ó kí n wá lo tèmi
(Agbájé, 1989)

Ewì òkè yìí ń ṣe àfihàn pàtàkì ewé àti egbò láwùjọ Yorùbá.

Pépà yìí rọ̀ wá pé kí a ṣe àmúlò ewé àti egbò tí Èdùmàrè fi jíǹkì wa láti fi mu àlàáfíà wà fún tẹrú-tọmọ ní àwùjo. Òtíítọ́ ṣáà ni pé kí ìwòsàn òyìnbó tó dé, ọ̀nà tàbí ìlànà ìbílẹ̀ ni àwọn baba-ńlá wa ń gbà ṣe ìwòsàn. Iṣẹ yìí rọ gbogbo ọmọ Yorùbá láti gbárùkù ti ìwòsàn ìbílẹ̀ nítorí “tẹni-n-tẹni, èkísà-n-tàátàn”. Iṣẹ́ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ewé àti egbò (oògùn ìbílẹ̀) wúlò ni gbogbo ọ̀nà pàápàá jùlọ fún ìdáàbòbò, ìdènà àti ìwòsàn onírúurú ipenija ailera tí ń ba ẹ̀dá fínra láwùjọ wa. A dá a lábàá pé kí a túnbọ̀ mójú tó bí ìmọ̀ ìṣègùn ìbílẹ̀ yóò ṣe gbẹ̀rẹ̀gẹ̀jigẹ̀ tí yóò sì tún gòkè àgbà lágbàáyé dípò fífi ẹnu ṣáátá ẹ̀bùn pàtàkì tí Elédùà fi jíǹkì wa nílẹ̀ Adúláwọ̀.

**Ìwé Ìtọ́kasí**

Abdulbaqi, A. (2002). HIV cure give folk medicine the upper hand. www.islamonline.netlenglish/science/2002/11/article07/shtml.

Abímbọ̀lá, W. (1982). "A Notes on the Collection, transcription, translation and analysis of Yorùbá and Literature", In Afọláyan, A. (ed) Yorùbá Language and Literature. Ife: University of Ifẹ̀, P. 78.

Adéloyè, A. (2015). *History of medical practice in Nigeria.* Stirling-Horden Publishers Ltd.

Adéoyè, C.L. (2005). *Àṣà àti iṣe Yorùbá.* University Pres Ltd.

Adékẹmi, T. (2016). Àmúlò Ìṣègùn Ìbílẹ̀ fún Ìtọ́jú àìsàn ibà Jẹ̀funjẹ̀dọ̀ àti Ẹ̀jẹ̀ Ríru ní ilẹ̀ Yorùbá. Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Èdè Yorùbá. 8, (2), Pp. 72-84.

Adéyemí, L. (2006). *Tíọ́rì lítíréṣọ̀ ní edè Yorùbá.* Shebíotimo Publications.

Agbaje, B. (1989). "Iṣẹ́ Ìṣègùn" nínú Ilésanmí T.M. (ed) *Iṣẹ́ Ìṣẹ̀ḿbáyé.* Ilé Ifẹ̀; Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press. o.i 296-321.

Ajíkòbi, O. (1999). Ìṣègùn Ìbílẹ̀: Ẹja N 'Bákàn? *LÁÀǸGBÁSÀ, 8,* 73-92.

Àránsí, A.O. (2017). Ìlò Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé fún Ìpolongo Oògùn Ìbílẹ̀ Yorùbá. *Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria,* 8 (4) 72-98.

Bámidélé, L.O. (2003). *Literature and Sociology.* Striling Horden Publishers Nigeria Ltd.

Fáṣehùn, M.A ati Adébóyè, J.O (2019). Àfihàn ilò oògùn ibílẹ̀ Yorùbá nínú aṣàyàn iṣẹ́-onà Adébáyọ̀ Fálétí. *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ Èdè Yorùbá Kọ́lẹ́ẹ̀jì Ẹ́ń-siii, Nàìjíríà,* o.i 478-489.

Ìṣọ̀lá, A. (2010). *Making culture memorable.* Hope Publication Ltd. & DB Martoy Books.

Òjó, F. (2009). Yorùbá indigenous medicine in scientific and technological advancement in Akorede, Y.,Ògúnsíji, Y. M., and Boko, G.C. (Eds), Language, Literature in the Current Technological World. P. 121.

Olomu, O.O (2019). Ontological Essence of Ifa and Osanyin in Yoruba Indigenous Healthcare system. LASU Journal of Portuguese studies, 3, Pp. 226-243.

Orimoogunje, O.C. (2015). The Yoruba Indigenous healthcare delivery system: A preliminary study. EBSU Journal of society 4(1), Pp. 23-31.

Ọ̀ṣọbà, B. ati Ọ̀ṣọ́, F. (2016). Ìlò oògùn fún idáàbòbò nínú awọn ìwé Fágúnwà. *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀-Èdè Yorùbá.* Pp. 179-185.

Oyèbámijí, A.K. (2016). Ipá Lítíréṣọ̀ àti iṣègùn ibílẹ̀ Yorùbá nínú etò aàbò orílẹ̀-edè Nàìjíríà: Oriíawẹ̀ Àdìgún àti agékù-ejò gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n. *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá Ẹ́ń-siiì, Nàìjíríà.5* (1), 198-208.

Oyèlákin, R.T. (2009). Yorùbá traditional medicine and the challenges of intergation. *Journal of Pan African Studies,* 3(3).

Rájí, S.M (1991). *Ìjìnlẹ̀ ọfọ̀, ogèdè àti aásán.*Onibonòjé Press Ltd.

Rájí, S.M (2014). Ojú Àmúwayé Yorùbá nípa oògùn ibílẹ̀ fún aàbò orílẹ̀-èdè. *Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá Kọ́lẹ́ẹ̀jì Ẹ́ń-siiì, Nàìjíríà,3*(1), 159-171.

## Àwọn Abẹ́nà Ìmọ̀

| **Orúkọ** | **Ẹ̀yà** | **Ọdún lẹ́nu iṣẹ́** | **Ọjọ́-orí** | **Àdírẹ́sì** | **Iṣẹ́** | **Ọjọ́ ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò** |
|---|---|---|---|---|---|---|
| Orítóókẹ́ Herbal home | Obìnrin | Mẹ́tàlá | Mọ́kànlélógójì | 50, Ìbàsà Rd. Ìjànikin, Ìyànà-Ẹrà | Oníṣègùn ìbílẹ̀ | 24/6/23 |
| Táwà Ṣítù (ìyá Gbọ́láhàn) | Obìnrin | Ọgbọ̀n | Méjìléláàádọ́ta | Ojo water side Ojo Aláwọ̀rọ̀ Market | Alágbo/Eléwé ọmọ | 26/6/23 |
| Mọ́ríámọ̀ Ọládipúpọ̀ | Obìnrin | Mọ́kànlá | Mẹ́rìnlláàádọ́ta | 7, palace Rd. Ọ̀tọ̀-Àwórì | Alágbo/Eléwé ọmọ | 27/6/23 |